# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL: I. NO. 11. SATURDAY, SEPTEMBER 23, 1922. THREEPENCE.

*Editor:*—ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣe si *Editor*

### GBOHUN-GBOHUN.

### Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!!!

A ni 'reti pe ọpọlọpọ awọn ọrẹ wa ni yio fi tayọtayọ tọwọ bọ apo wọn lati jẹ ipe wa, nipa irohin Ipade-Ilu kan ti a ṣe nilọlọyi, eyi ti ọrẹ wa FANOKUN rohin rẹ sinu Iwe-Irohin ọsẹ yi: ẹniti o ṣe Akoso Ipade na ni Ọgbẹni J. A. OSHODI, OMO "ORU-NDU A RU LOGUN BI EFI:" BOKINNI yi si mu i'leri to ṣe ni Ipade na ṣẹ nipa fifi pọun kan ṣile kan (£1 : 1 : 0) ṣẹ wa lọwọ. A tọrọ Ibukun Oluwa fun ẹni wa yi: a si ni ireti pe awọn ara wa toku ki yio lọra lati ṣe bi ipa wọn ti mọ si iṣẹ yi.

### IBOSI OWO!

Ninu Iwe-Irohin Ijọba, *(Nigeria Gazette)* ti ijọ kẹrinla oṣu yi, a ri i ka pe Ijọba npete ati bu owo si Otitẹ t' a nlo fun oriṣiriṣi takada, *(Stamp Duties)* koi ti i di Ofin ṣa.

### KINNIUN ONIBUDO ATI LỌYA JIGA T' AJO BỌ.

Awọn Ọgbẹni wa mejeji yi (Herbert Macaulay, J. Egerton Shyngle) ti ajo bọ ni ọjọ diẹ sẹhin, a ki wọn "Kabọ."

### "TA A NI BATA, KO ṢUBU, KO PẸJỌ."!!!

A ko tete gbọ pe ọrẹ wa E. JENKINS HARRISON Amofin, dalẹ lọ si CALABAR ni iwọn ọsẹ diẹ sẹhin fun iṣẹ kan nibẹ.

## ADAJỌ ABẸRIN ṢE-FUJA.

A gbọ pe Adele Adajọ Agba OLOLA A. R. PENNINGTON nfẹ ṣe "Awowo" kan ni ọjọ kẹfa oṣu to mbọ, ni Ile-Onjẹ Ataba-tibi *(Grand Hotel)* ni Opopo-nla.

## OLE AFINJU.

Ihin kan ni pe awọn kan wa ti nwọn nwọle ji *Bicycle* oni *Bicycle* nisinsinyi; a sọ pe o jẹ aṣa wọn lati ma gun un gẹgẹ bi ẹnipe ti wọn ni, laile mu enia fura pe nwọn ji i ni. Irufẹ awọn Igara bayi ko gbe enia ta ti!!!

## KỌNGRẸS ỌRỌMIDUN ILU AGANYIN.

Ohun ti o mu mi gbidanwo ati mu ero wa lọ si ilu Aganyin nisisiyi ni ero kukuru ti o wa ninu awọn enia wa nipa ti ọrọ ilu; bi a ko ba si ngbidanwo ati ma gbọ iro ilu miran, ọpọlọpọ asiṣe ni yio ma wa ninu iṣelu wa. Ọrọ ti Kọngrẹs jẹ Ọrọmidun gbogbo Ilu Aganyin, awọn ti o jẹ pe ko bikita fun Ẹgbẹ yi kere pupọ, ṣugbọn Enia pataki diẹ wa ninu wọn, awọn bi NANA OFORI ATA, Ọba Akyim Abuakwa E. J. P. Brown, ọkan ninu enia dudu ti Ijọba yan si Igbimọ asofin ilu *Legislative Council*, J. P. Brown, Biney Baba Ẹgbẹ gbogbo ilu Aganyin *Aborigines Society*. JOHNSTON Akọwe Ẹgbẹ yi. A o ṣe iranti pe n'gbati awọn ikọ ti a ran lọ si ilu oyinbo lati ilu mẹrerin ti nbẹ labẹ ijọba Gesi de ilu Oyinbo ti wọn si fi iwe ẹbẹ sọwọ si Ọba, *King George* NANA OFORI ATA Ọba Akyim Abuakwa jẹ ikan ninu awọn ti o wa ni igbimọ asofin ilu, o si sọrọ ibajẹ pupọ si Ẹgbẹ gbogbo enia dudu yi, ninu ọrọ rẹ o si sọpe gbogbo Ọba ti o ku patapata ni ilu Aganyin lo ran on ni iṣẹ ti on njẹ yi ati pe awọn ko si fẹ Kọngrẹs rara, bi nkan ba ndun awọn gẹgẹ bi alaṣẹ ilu Aganyin, awọn o da iwe kọ si Ijọba lai papọ mọ ilu omiran; wara were Ijọba nwọn ti fi ẹrọ mọnamọna ranṣẹ si ilu oyinbo wipe gbogbo Ọba Ilu Aganyin ko lọwọ ninu Kọngrẹs yi ati nitorina ki Ọba KING maṣe teti si ẹbẹ ti o wa ninu iwe na. Ni akoko gbogbo ti a fi nṣe eyi, gbogbo ilu ko gbọ nkankan titi nwọn fi wa ri gbogbo ọrọ ti NANA OFORI ATA yi sọ ka ninu iwe irohin ilu oyinbo. Nigbati awọn Ọba ti o ku gburo iwa ika ti NANA OFORI ATA yi hu si Kọngrẹs ati pe o si purọ mọ wọn, gbogbo wọn dide, nwọn ṣe ipade Ẹgbẹ wọn (*Aborigines Society*) gbogbo awọn Ọba ti o pe sibẹ si fi ohun ṣọkan pe ki a tẹ *Wire* ranṣẹ si Gomina ati Akọwe ilu ni ilu Oyinbo pe irọ ni OFORI ATA pa mọ wọn, ẹnikẹni ko si ran niṣẹ ti o jẹ ni Ajọ Igbimọ asofin ilu ko pe lẹhin eyi, awọn ti a ran lọ si ilu oyinbo pada bọ, Ọgbẹni Caseley Hayford ẹniti o jẹ ọkan ninu awọn igbimọ asofin ilu, wa ninu awọn ti Ilu Aganyin ran lọ si ilu oyinbo o si sọ fun Gomina pe on fẹ sọrọ lori Ọrọ Kọngrẹs ni Igbimọ, "Ologinni sa tajẹ bọ; ki gbogbo Ekute ile ma paramọ; n gbati ọjọ pe ti gudugbẹ ma ja, gbogbo ilu lo pe sinu ile gẹgẹ bi ero iworan lati fi oju ganni ija iwe ati ọgbọn, ẹda bi Caseley Hayford di ṣaṣa ni ilu Aganyin; I' ọjọ yi o sọrọ lọ bi ilẹ bi ẹni, O bẹrẹ si ṣi lawẹlawẹ, O si fi han pe, ijọba papa o dabi ẹnipẹ awọn lo nba Ẹgbẹ yi ṣe akitiyan, ti nwọn si nran OFORI ATA lọwọ, nitoripe bi iwe irohin ti pọ to ni ilu Aganyin, ijọba ko ri eyiti o le tẹ ọrọ ti OFORI ATA sọ sinu rẹ afi ti ilu oyinbo; O wa tun bere o ni gbangban d'ẹkun, kedere lẹ ẹ wo, ki OFORI ATA wa sọ nibo ni awọn Ọba ilu Aganyin gbe pade ti nwọn fun laṣẹ ati so ọrọ mugun gbogbo ti o sọ, o di wọni nwo ẹ, OFORI ATA ni ẹjọ on kọ, o ni awọn ti a yan ni igbimọ (*Aborigines Society*) Ẹgbẹ awọn Ọba onilẹ *Natural rulers* awọn bi Biney, awọn lo kọ iwe si on pe bẹni gbogbo Ọba sọ. Ni ijọ ọrọ yi gbogbo ilu ti pe si ita, nigbati Caseley Hayford pari ọrọ re nijọna, atẹwọ pa ariwo ayọ si lọ soke, pe adupẹ lọdọ Ọlọrun fun iru awọn enia bayi. Lati igbayi ni awọn ọlọgbọn ti wa bi sẹhin nwọn wa bẹrẹ si we ewe ati tun gbogbo nkan ṣe, awọn Agbalagba ilu tun Ṣokoto wọn san giri, nwọn ni eyiti awọn wa mọ awọn ti o nṣe wọn yi, ọrọ na ko ṣoro mọ.

Awọn Ọba ilu tun pejọ, nwọn ni ki Biney, ati awọn Ẹmẹwa rẹ ti awọn yan bi alaṣẹ Ẹgbẹ wọn *Aborigines Society* ki wọn wa sọ nibo ni awọn joko si ti awọn sọ wipe ki Ofori Ata lọ sọ pe awọn ko fẹ Kongres, ọrọ yi d' ọran. awọn Ọba wa sọ pe o dara, ẹniti o bajẹ ti bajẹ na, ẹniti yio b'alumọ loku, ki awọn alaṣẹ Ẹgbẹ kanna yi ti nwọn sọ pe gbogbo Ọba ilu Aganyin sọ pe awọn ko fẹ Kongrẹs, ki nwọn si tun tẹ *Wire* si Ọba ni ilu oyinbo pe, gbogbo Ọba ilu lo wa fun Kongrẹs, ọrọ yi d' ero, d' ete, awọn ọkunrin kọ wọn ko tẹ *Wire* na, awọn Ọba binu, wọn wa fi aṣẹ fun Ọba *Cape Coast* pe ki o tẹ *Wire* na. Nwọn wa tun fi apejọ Ẹgbẹ si osu *June* ti o kọja yi, wọn si sọ fun Biney ati awọn ti o ku pe, ki wọn wa ṣiro iṣẹ iriju, wọn, ati pe nwọn ko gbọdọ lo aṣẹ kankan titi ọrọ wọn yio fi yanju ni ajọ ti o nbọ.

Ki akoko ti awọn Ọba da, Biney gẹgẹ bi ipo rẹ, on ati awọn ti o wa ninu tirẹ tun lo aṣẹ Ẹgbẹ yi lati kọ iwe si ijọba nipa yiyan enia si igbimọ asofin ilu; nigbati ọjọ pe ti gbogbo awọn Ọba ilu Aganyin de si *Cape Coast* gbogbo awọn Agbagba ilu wa nibẹ pẹlu, awọn bi Caseley Hafford, Van Hein olowo soke d' ilẹ, Kobina Sekyi ọkan ninu awọn amofin, ọmọkekere patapata ni ṣugbọn ifẹ ilu rẹ jẹ l' ọkan pupọ ju, ẹsẹ pe, awọn obilẹjẹ sa, wọn kole wa f' oju kan olowo wọn, awọn Ọba wa gbe onişẹ dide pe awọn ti bẹrẹ ajọ, ki nwọn ma bọ wa ṣiro iṣẹ iriju wọn, O wa d' ẹti, ati y' ọju ko ya, gbogbo wọn wa bẹrẹ si sa kiri, nigbati o di pe nwọn ko fẹ wa, a wa ran onişẹ ki nwọn lọ mu wọn lọwọ morun wa: Johnson Akọwe ni ọwọ kọ ba a si mu lọ si ile tubu Ọba ilu Ki awọn ara rẹ to wa duro fun di ijọ kẹji; a tun ran awọn onişẹ ki nwọn lọ ko awọn to ku wa, nigbati wọn fi oju kan wọn, o di gidigidi ọwọ ko raye ba wọn, awọn ti a ran wa pada jiṣẹ fun awọn ọba ni ipade; awọn ọba binu pe bi o ti ma ri lo ma ri, gbogbo wọn wa dide, o di ile Komiṣọna (*Commissioner*) nwọn si sọ fun oyinbo pe ti awọn ko ba fi ri wọn, awọn o ranşẹ lọ bo ile wọn; Komiṣọna bẹ wọn O si sọ pe on yio fun awọn ọkunrin na ni imọran pe ki nwọn wa da awọn Ọba ilu wọn lohun; ki a ma da lọ werẹ, nigbati a fi ma mu wọn lọwọmọrun wa si waju awọn Ọba ilu, o di ẹbẹ.

A wa fi agbara mu nwọn ko gbogbo iwe, otitẹ ati gbogbo nkan Aṣẹ ti a ti ko fun wọn wa a si yọ won patapata ninu igbimọ ti awọn Ọba ilu Aganyin. Orukọ awọn ti a le kuro ni iwọnyi, E. J. P. Brown ikan ninu awọn ti ijọba yan si Igbimọ Asofin ilu (*Member of the Legislative Council*) J. P. Brown ti o nşe iwe irohin ti awọn Ọba ilu Aganyin (*Editor of the Gold Coast Nation*) J. E. Kitson. J. Andrew Wilson, Ebenezer H. Brew, alufa Gaddiel R. Acquaah ati W. S. Johnston, a si tun tẹnumọ fun awọn igbimọ titun pe laiyelaiye nwọn ko gbọdọ fi aye silẹ fun awọn ti a le wọnyi lati tun wọnu igbimọ yi mọ. Owo tia bu fun wọn ti wọn si san lẹiyẹ o jẹ Poun Mọkanlelogun ati ṣile Mejila, Apoti Oti Whiskey Merin, ati Akọ Malu kan; awọn Ọba si pa Malu yi nwọn fi ṣe etutu gẹgẹ bi aṣa ilu wọn. A fi oju anu wo Biney, a si fi silẹ gẹgẹ bi ọmọ Ẹgbẹ. Bayi ni a ṣe pari ọrọ batakunbatakun yi ti o fẹrẹ da oju ilu Aganyin de; gbogbo ilu wọn lo fẹ Kongrẹs ṣugbọn awọn ti a wa yọ yi ati Ọba bi mejiṣa lo jẹ idina diẹ fun.

Ẹniti a fi jẹ Baba Ẹgbẹ nisisiyi njẹ Van Hein on si ni akapo Ẹgbẹ ti Kongrẹs; ki a tọrọ ẹmi gigun ki Ọlọrun jẹ ki akoko tirẹ dara.

O yẹ lọpọlọpọ ki a fi ti ilu Aganyin k' ọgbọn, ki a si bere pe kini mu ilaju pupọ wa si ilu Aganyin, ohun ti o mu eyi wa nipe, gbogbo Ọba wọn lo fẹrẹ mọ iwe tan, bẹ si ni awọn Ijoye wọn amofin nbẹ ninu wọn pẹlu, ko dabi tiwa nihin; Ẹ jẹ ki a mura ki awọn Oloye wa ma ran awọn ọmọ wọn lọ si ile-iwe ki a si kọ wọn, ki wọn ja faufau ninu ẹkọ, nipa ṣiṣe eyi, ọpọlọpọ ibi ti o nba wa nipa aimọ iwe awọn Oloye ati awọn Ọba wa yio buku.

FANOKUN.

EKO AKETE.

Eko, Saturday, September, 23, 1922.

## ABI-IKỌ BABA AKỌ Ọ-'GBỌN.

O jẹ ohun irira fun ni nigba pupọ ti a ba nri ninu awọn enia wa to jẹ Imale ti nwọn ki i ronu diẹ lati ma a da orin isọkusọ silẹ nigbamiran ti nwọn ba njo kiri papa lọjọ ọsẹ: a ko sọ pe o jẹ ẹṣẹ tabi alebu fun ijo ti nwọn njo lọjọ yi, ṣugbọn ohun ti a ntọka si ni ti orin isọkusọ lati ma a darukọ ibi aṣiri lara, ti ki i ti t'ọmọde-t'agba wọn loju lati ma a kọ kakiri igboro; o to igba meji tabi igba mẹta ti a nṣeṣi ba irufẹ awọn enia bayi pade: ninu gbogbo akoko yi, ni a ni lati fi ọwọ di eti wa fun o in ti Omoluwabi kan ko jẹ daba ati ma a kọ, afi ọmọ ina: ohun to si tun ya wa lẹnu lori gbogbo rẹ ni pe Ọlọpa ki nlala ati da wọn lẹ kun irufẹ orin bẹ ẹ, tabi ko mu wọn ni mọwọ-mọrun ti nwọn ko ba gbọ ọrọ si i lẹnu.

Nigbati a ba nri bale-ile to nsigbala kakiri ita bi ẹṣin to ti ja lori-'so, to si nlu igo ofifo fun ijo to njo pẹlu orin Masondoki lẹnu, ogo ni awọn ọmọ rẹ tabi awọn miran ti ko to ntẹlepa ọna palapala wọnyi. Njẹ a bere, kinni irufẹ iwa yi, bikoṣe Iwa Abi-Ikọ. Iwa Abi-Ija'bi-Lọrun? A dupẹ pe ki iṣe gbogbo awọn ẹni wa to jẹ imale ni o ni iwakiwa yi lọwọ. A si bẹ awọn ti o njẹbi iwa yi ki wọn fi ẹdẹ si i, nitoripe lai si tabitabi, kosi ẹniti ko mọ pe "Ọrọ buburu a ma a ba iwa rere jẹ." Sugbọn iye awọn ti ko ba gbọ ẹbẹ yi, a bẹ awọn Oikri Ọlọpa Ilu ti funfun ti dudu, ki nwọn ma ṣai fi ẹnikan ṣapẹrẹ irufẹ eleti-kunkun bẹ ẹ, ẹniti a nwo lawo-sọkun ti o nwọ ara rẹ lawo-rẹrin, ti o si nṣebi on nṣe nkan gunmọ loju ara on ni. Ọrọ Isọkusọ bi Ẹja ko yẹ Ọmọ Enia.

---

### ELETI ỌFẸ ati AWỌN IMALE EKO.

Lati ẹnu Ọsẹ melo yi wa ti a ti nka Iwe irohin yi ni a ti nri ọpọlọpọ aiba'kun pade ọrọ ti "Eleti Ọfẹ" ti nsọ nipa ti awọn enia wa ti o jẹ Imale, bi o ba jẹ pe ohun gbogbo ti o nsọ jẹ otitọ a ki ba ti sọrọ, ṣugbọn nigbati a ba si ri pe o nṣisọ bayi, o yẹ ki a fi aṣisẹ rẹ han ni ṣoki.

ẸKINI. O pe awọn "Jamat Mussulmi" ni Ilu ki iṣe awọn nwọnyi nikan lo ngbe inu Ilu Ẹko, awọn Onigbagbọ orişirişi, awọn Imale orişirişi, ati awọn ti o nsin Ọlọrun l'ọna ti Ilẹ wa lo gbe inu rẹ.

ẸKEJI. O si tun nsọ bi ẹni pe orişi Imale miran ko si mọ, awọn bi "Ahmadia" ti o nkirin lẹhin Lemọmu Dabiri, ati awọn "Alalukorani;" A ko le sọ pe nitori awọn Ṣọṣi ti Anglican ṣe nkankan ti a ro pe ko t'ọna ki a bẹrẹ si gbogbo Onigbagbọ lati ma bu.

ẸKẸTA. O nfi Lemọmu Buraimọ we *Bishop*, ipo ati iduro awọn mejeji yatọ si ara nwọn patapata, ẹya isin Onigbagbọ ti a njẹ *Bishop* ninu rẹ jẹ eyiti o ti Ilu ajeji wa, iya nwọn nbẹ ni Ilu Oyinbo, ọmọ si ni awọn ti Ilu wa nihin jẹ, orukọ Iya yi ni a si fi ngba Ilẹ lati kọ Ile Ọlọrun, ẹniti o ba si fẹ ni fi jẹ oye *Bishop* ti isi fi ṣọwọ sibi, ati Ilu Oyinbo ni *Bishop* ti wa pẹlu aṣẹ, enia dudu kan ko si l'aṣẹ lori *Bishop* rara; isin Imale ti awọn oni Jalailu ko ri bayi, nwọn ko ni Iya nibi kibi, ẹniti o wu nwọn ni wọn fi njoye, nwọn ni aṣẹ Mọṣalaṣi wọn, nitoripe owo nwọn ni nwọn fi kọ, ati lori Lemọmu nwọn nitoripe awọn lo fi jẹ.

Ki a wa bere kini pataki Ija ti o wa larin Lemọmu Buraimọ ati awọn Janma rẹ (Jamat Mussulmi,) pataki rẹ ni pe awọn ti o pọ ninu Ijọ rẹ fẹ ki Lemọmu gba ọna kan, awọn apakan ti o kere, lati igbana ni iyọnu ti de, nko si ro pe ni Ilẹkilẹ, ẹni ti o fẹ jẹ Oye le ṣe iru eyi, ki ariwo ma ta, nitori "Ẹdiẹ ba l'okun, ara o r'oku, ata o r' Adiẹ."

Owe kan nbẹ ni Ilẹ wa wipe "ti a ko ba to Ija la, a ki i da kun" mo ni ireti pe "Eleti Ọfẹ fẹ la Ija ni, ṣugbọn gbogbo Iwe ti o nkọ fihan gbangba pe o tun bọ nda kun Ija ni, yio si jẹ ohun ti yio ṣe anifani pupọ, ti o ba kọ Iwe lati fi ohun miran ye wa ju ti Ija Lemọmu ati awọn Ijọ rẹ, eyiti Ijọba ti sọ ninu rẹ pe Ija Isin ni awọn ko si le da sinu rẹ.

---

### IROHIN KUKURU TI IPADE TI A ṢE NI ILUPESI NI FRIDAY ỌJỌ KẸDOGUN OṢU SEPT., 1922.

Niwọn agogo mẹfa lẹhin ti a ti gbadura, Ọgbẹni J. A. Oṣodi ẹniti a yan ṣe olori Aga ninu ipade yi pe Professor Deniga oniwe irohin "Eko Akete" lati la alaye eredi rẹ ti o fi pe apejọ yi. Oniwe irohin yi ninu ọrọ rẹ sọ wipe ni ipade ti o kọja ni a fun on laṣẹ lati tun pe ipade miran fun ati wa

ọna ti Ilu yio fi ran on lọwọ nipasẹ Owo niti Iwe irohin ti on jẹ Alakoso rẹ.

Ọgbẹni Dabiri Ọdunsi ati Alufa Campbell sọrọ pupọ lori iṣẹ Iwe irohin ati bi o ti tọ ti o si yẹ lati ran eyiti a nṣe lede Ilẹ wa lọwọ daradara.

Olori aga sọ bi o ti dun mọ on ninu lati wa si ipade yi, ti a sin yan on ni Alakoso re; o sọ bi o ti dun mọ on ninu nigbati on ri Iwe irohin ti a tun ntẹ lede wa ti oniwe irohin si sọ orukọ rẹ ni "Eko Akete," ile ogbọn arọdẹdẹ ma ja," o sọ bi o ti jẹ pe ọpọlọpọ Iwe irohin lo ti wa ri ti o sin ti ku nisisiyi nitori airi iranlọwọ to bi o ti tọ ti o si yẹ, o ni ni Ilu Oyinbo, iwe irohin pọ nibẹ owo rẹ si kere pupọ, nitori ọpọlọpọ enia lo ngba a, iba ṣe lojojumọ tabi lọsọsẹ, eyi jẹ iranlọwọ pupọ fun ẹniti o ba nṣe Iwe irohin, nitori nigbati ẹniti o ngba ba pọ laimoye, oniwe irohin yio ma ri owo gba daradara lati fi san owo awọn Oniṣẹ ati lati fi pamọ si apo isingbẹ, yio si le ma sọrọ fanda bi o ti ye, ṣugbọn ni apa Ilẹ wa nihin eyi ko ri bẹ, awọn ti o ngba Iwe irohin ko pọ to, a ko si ma nfi tinu-tinu ṣe iranwọ ti o jọju fun awọn ti o nṣe e, eyi jẹ ohun alebu o si yẹ lọpọlọpọ lati ma ran nwọn lọwọ lọnakọna, nitorina yio dun mọ on lọpọlọpọ bi a ba le ṣe ipinnu kan pe ki Oniwe irohin "Eko Akete" gbe Iwe jade lati tọrọ owo fun iranlọwọ Iwe irohin na.

Alufa Campbell si mu ipinnu na wa pe "O jẹ" "inu didun ipade yi lati fun oniwe irohin "Eko Akete" ni aṣẹ "pe ki o gbe Iwe jade lati tọrọ owo lọdọ awọn" ara Ilu fun iranlọwọ iwe irohin "Eko Akete" Ọgbẹni Orioye gbe e lẹsẹ, gbogbo ajọ sin gba.

Lẹhin ti a ti gba ipinnu yi Olori aga si sọrọ iṣiri fun Oniwe irohin, o si fi aṣẹ si i pe ki o gbe Iwe jade gẹgẹ bi ipinnu ti a gba yi, on si ni iamma pe pẹlu agbara lọdọ Ọlọrun yio ri iranlọwọ ti o tọ ti o yẹ gba.

Alufa Campbell fi adura pari ipade nwọn agogo meje kọja diẹ. Olukaluku ẹniti o wa si ipade yi lo fi itara ati ayọ han fun iwe ti a ntẹ ni ede wa, ko tun si pe a ra iwe tan a sin tun nwa ẹniti yio ma tunmọ rẹ fun ni, ẹnikẹni ti o ba ti le gbidanwo ati mọ A. B. D., o di ọga ni yẹn ki o si ma kọ Ẹkọ bi a ti nṣe Ilu, ati lati ma gbọ bi a ti nṣe kakiri aiye.

Njẹ ẹnyin ara mi, ati fi aṣẹ fun Professor Deniga lati tọrọ owo fun iranlọwọ Iwe irohin rẹ, a sin ke si gbogbo enia l'ọkọnrin l'obinrin lati ṣe iranwọ gẹgẹ bi agbara rẹ ba ti mọ.

FANOKUN.

## IPO AWỌN ỌMỌDE.

Eko,
23rd September, 1922.

LETTER NO. 9.

Ẹnyin Ọrẹ mi ọwọn,

Inu mi dun lati sọ fun nyin pe gbogbo ọrọ ti a ti fi ngba nyin li iyanju lati ọjọ yi wa ki iṣe pe ki ẹ ma ka wọn nikan; ṣugbọn ki ẹ ma fi wọn ṣe iwa hu, nitori ki iṣe kika wọn lasan li a nṣe nkọ wọn bi ko ṣe pe ki ẹ ma fi wọn ṣe iwa hu. Bi ẹ ba ka wọn lasan, wahala wa yio jẹ si asan, ṣugbọn bi ẹ ba nfi wọn ṣe iwa hu, nigbana ni inu wa yi o ma dun gẹgẹ bi olutọju awọn ọmọde, nitori owe kan sọ pe, "Ẹyin li o ndi akukọ."

Ọrọ ti mo fẹ fi gba nyin li iyanju lọsẹ yi li ỌWỌ FUN AWỌN AGBA, eyiti oyinbo npe ni *respect to elders.*

Nkan kan li mo fẹ ki ẹ mọ lati igba ewe nyin lọ eyi iṣẹ ẹda ti ẹnikẹni kole yi pada, eyi ni pe ohunkohun ti enia ba gbin li o ma ka bẹ na li iwa gbogbo ti enia nhu, ibaṣe iwa rere tabi buburu, gbogbo rẹ o dabi irugbin kekere ti o ni lati so eso rẹ nigbati o ba pẹ titi. Bẹ na li o ri fun iwa ti enia nhu pẹlu. Iyẹn ni iyẹn.

Ọrọ wa ni pe ki ẹ ma bu ọwọ fun awọn agba ati pẹlu pe ki ẹ kọ lati ma fi ipo agba fun agba.

Papa ẹnyin ọmọde, ẹ ni lati bọwọ fun awọn obi nyin ati awọn olukọ nyin. Nigbamiran ni Ile Ẹkọ ọpọlọpọ ọmọ miran wa ninu nyin ti ki ifẹ lati ma bọwọ fun awọn ti ki ba ṣe olukọ wọn, eyi ko dara ẹnikẹni ti o ba ju nyin lọ, ẹ ni lati bọwọ fun u.

Kinni nmu Aibọwọ tabi Afojudi (*Disrespect*) wa? Iwa omugọ, igberaga ọkan; ohun ti awọn ọmọ alafojudi ma nro lọkan wọn ni eyi, "Emi ki ng bọwọ fun eleyi, eleyi kẹ, kini le ṣe fun mi," irotẹ ọrọ bayi li o ma nti ẹnu wọn jade, papa lati ọdọ awọn ọdọmọbinrin, bẹ ni nwọn ko mọ pe nwọn ngbẹ iho iparun silẹ fun ara wọn ni, nitori ohunkohun ti enia ba gbin li ó ma ka.

Ẹnyin ọmọde, ki a ma tan yin jẹ, ẹma bọwọ fun awọn aṣiwaju nyin nitori eyi li aṣẹ Ọlọrun, "Bọwọ fun baba on iya rẹ ki ọjọ rẹ ki o le pẹ nilẹ ti Oluwa Ọlọrun rẹ fi fun ọ." Ẹnikẹni ti o ba nfẹ ki ọjọ on ki o gun si rere ki o ma bọwọ fun awọn agba. Ẹ ma ki awọn obi nyin pẹlu ọwọ. Ẹ ma tẹriba fun wọn pẹlu.

Ibọwọ fun agba ọtọ oju-isaju (*Eye-Service*) ọtọ Awọn ọmọde miran wa, ti o jẹ pe bi nwọn ba ri oju obi wọn ni wọn ma nbọwọ fun wọn, ṣugbọn bi oju wọn ba kuro, wọn a bẹrẹ si iwa afojudi ihu, ati ni Ile-Ẹkọ pẹlu bi olukọ ba wa ni yara Ile-Ẹkọ pẹlu wọn, nwọn a ma bọwọ fun u,

ṣugbọn bi oju rẹ ba ti kuro, nwọn a bẹrẹ si huwa bi ọmọ ti ko ni ẹkọ, irufẹ iwa bayi ko dara, agbagebe ni, iwa ẹtan ni, iwa oju isaju si ni pẹlu. Bi ẹnikẹni ba nṣe bayi larin nyin ki o fi i silẹ ko dara. Irufẹ eyi ko li a nko nyin, ṣugbọn ohun ti a nkọ nyin ni pe ki ẹ kọ lati ma bọwọ fun wọn loju wọn ati lẹhin wọn.

Ẹ ma toju iṣẹ nyin. Ohunkohun ti awọn aṣiwaju nyin ba ni ki ẹ ṣe, ẹ ma ṣe e towọ-towọ ati pẹlu itẹriba. Ọrọ gbogbo ti awọn obi nyin ati awọn olukọ nyin ba mba sọ ẹ ma fun wọn li esi pẹlu ọwọ ati itẹriba.

Mo pari iwe mi pẹlu ifẹ.
Emi ni ti nyin nitotọ,
ELETI-ỌFẸ.

## AKIRIMANU.

Bi o ti jẹ pe o tọ ki a ma ṣi ara wa leti nigbagbogbo fun irẹ ilu wa ati awa papa. Emi AKIRIMANU gbiyanju lati sọ diẹ ninu ohun ti mo ti nṣe akiyesi.

A ri pe iwa ole ndagba larin awọn ọmọ wa nipa rira ẹyin Awo ati Adiẹ ti nwọn fi nta tẹtẹ ati pe aṣa yi pọ tobẹ gẹ to jẹ pe oju nti ni, pataki ni *Marina* niwaju ile awọn oyinbo ọlọkọ (*E. D. & Co.*) lojojumọ, a o ri to iwọn ogoji awọn ọmọ wẹwẹ ti nwọn nsure s' ọtun ti nwọn nsure s' osi pẹlu ariwo gee, a o bẹ Ijọba pataki awọn ọlọpa ki nwọn ṣe iranlọwọ ati fi opin si iru aṣa imẹlẹ wọnyi. A ko le ṣe alai sọ ti awọn agbalagba papa, pataki awọn Hausa ni ọna Oko Awo, aṣa yi dabi ohun tulasi fun wọn. Ẹ jẹ ki a ni ireti pe Ijọba yio dide si iru ọrọ bayi. Kekere lati p' ekan iroko.

Lọna keji o da ni loju pe ki iṣe Mọmọdu nikan ni Anabi to wa lati ma fi bẹ Ọlọrun. A ṣe akiyesi pe awọn Gambari ati ara Ilọrin sọ ọ di aṣa lati ma fi orukọ Anabi yi tan aiye jẹ bayi:—"Ẹ bun mi nitori Mọmọdu yara sululai" "*Bani domin Muhammed yara sululai.*" Bayi ni awọn ti ntọrọ wọnyi nwi. Eyi mu ki a ro ni ọkan wa pe isin Mọmodu yi jẹ isin ti a le ma ta jẹun pẹlu ẹniti oju rẹ fọ ati eyiti ko fọ, gbogbo wọn lo sọ ọ di iṣẹ lati ma ke kiri ni alẹ nipa didarukọ Mọmọdu. mo ro pe Aṣa yi, dabi irẹjẹ. Bi a ba ṣe akiyesi, a le jẹri pe ki a to ri Onigbagbọ kan to ntọrọ ti jẹ pẹlu Orukọ Jesu di kese. A dupẹ pe Jesu jẹ *Ruhu-Lai* (Ẹmi Ọlọrun). Nkan wọnyi jẹ itiju fun wa, ati pe eyi si nrẹ isin Imale silẹ. Awọn miran sọ ọ di aṣa lati ma ke kiri niwọn ago mọkanla oru tabi mejila; nipa ṣiṣe ọgbọn lati gba owo lọwọ awọn omugo ẹgbẹ wọn. A o bẹ Ijọba (*Government*) ki nwọn ba wa fi akiyesi si iru iwa irẹjẹ yi. Awọn Oloriṣa ko jẹ ṣe iru iṣẹ ti awọn Imale nṣe wọnyi.

Ẹ jẹ ki a sọ otitọ ki Adaba fo. Mo nbọ ba ẹ, ma bọ wa, awọn mejeji ni ẹru mba.

A dupẹ lọwọ Onidajo nipa ayan ti o ṣe lati ẹjọ awọn awiyanu awọn Imale Eko. Gbogbo d' ẹkun kedere bẹ wo. O da ni loju pe on yio lọ so agbẹjọ mọ idi ara rẹ.

Ẹ o tun gbọ ohun mi—Akirimanu.

## ORIN BẸGBAJI SI AWỌN OBI

### GBIGBỌN ỌMỌ LERE ỌLỌMỌ.

Ọmọ meji lo yẹni,
Eyi to mọ oju eyi to m' ara,
Eyi ti ki i yago f' ẹni se 'bẹ kori bi jẹ
Ka wọn 'mi ata soju fun.
Iyẹn 'la npe li apa alaranjumọ.
Ọmọ to wu to ya 'pa, Igbakeji ẹranko ni,
Ẹni bi 'mọ ko sa a kọ
Ọmọ kole gọ titi katun gbọn lagbẹdẹ,
Ti ọmọ ba ti gbọn lo nje ere ọlọmọ.

Adupẹ lọwọ Ọrẹ wa Ọgbẹni Suberu Mogaji ti Ita Griffith, l'Okepopo to fun wa lorin iyebiye yi.
[Ed.—E.A.]

## Ẹ ṢO TITỌ, Ẹ ṢERERE ẸNI BA ṢO TITỌ NI MỌLẸ A GBE.

Gẹgẹ bi awọn akọrin wa ti ma yin awọn akọni enia to ba duro ṣinṣin ninu ohun gbogbo ti o ba dara, mo fi orin meji yi ki awọn agbede gbẹyọ ilu wa nihin.

### OHUN ORIN DANMỌLE

Jackson a ri re
T'oun pẹlu Deniga afinju ọmọ
Adamu wa jere, afye yin a dun titi m'alẹ
Ọlọrun Ọba a ṣọ wọn.
Ẹyin lọga agbede gbẹyọ fun wa nibi
Iwọ Misiwun mafọya Ọlọrun lododo Ọba
Ọba Oluwa a ṣọ wọn (oro aiye)
T' aiye tiya la a jẹpọ, kẹ mọ yẹn
Aiye a yẹyin tẹyin asunwọn Ẹ ri re.

### OHUN ORIN BẸGBAJI

Jackson kapẹ pẹlayọ
La k ọmọ olore
Ki Deniga ma foya to npel' Adamu
Misiwun wa pẹ wa a tagba ayẹ wọ

MAKANJU.

## ẸSU RIGIDI BO MI O!

OWO TI A ṢI RI GBA NI WỌNYI.

| | | £ | s | d. |
|---|---|---|---|---|
| Ọgbẹni | J. A. D. Kosokọ ... | 2 | 0 | 0 |
| " | J. A. Oṣodi... ... | 1 | 1 | 0 |
| " | Adam I. Yakubu ... | 0 | 5 | 0 |
| " | R. B. Ipayẹ ... | 0 | 5 | 0 |
| " | Saka Dabiri ... ... | 0 | 2 | 0 |
| | Total | £3 | 13 | 0 |

A o ma jihin yi lọsọsẹ,

[ED.—E. A.]

## LEGAL NOTICE.

In the Supreme Court of Nigeria.

In the matter of the estate of

ISHMAEL IDOWU OGUNTOLU. (*Deceased*.)

Notice is hereby given that all creditors having or pretending to have any claims or demands against the estate of Ishmael Idowu Oguntolu, late of 148, Strachan Street, Ebute Mẹta, (Lagos) Nigeria, deceased, who died on or about the 12th day of April, 1922, intestate, at 148, Strachan Street, Ebute Mẹta, (Lagos,) aforesaid, and Letters of Administration of whose personal estate were granted by the Supreme Court of Nigeria to me the undersigned Elizabeth Oguntolu, his widow, of 148 Strachan Street, Ebute Mẹta, (Lagos,) Nigeria, on the 15th day of August, 1922, are hereby required to send in particulars of their claims and demands in writing to me the said undersigned at the above address on or before the 30th day of December, 1922.

And Notice is hereby given also that after that date I will proceed to pay and distribute the assets of the said deceased among the parties entitled thereto, having regard only to the claims of which I shall then have had notice.

And all persons indebted to the said estate are required to make immediate payment of their indebtedness.

Dated the 29th day of August, 1922.

ELIZABETH OGUNTOLU,
*Administratrix*

## PREACHERS FOR TO-MORROW.

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

### ROMAN CATHOLIC.

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

| | | |
|---|---|---|
| ( Morning. ) | Masses | Isin Arọ. |
| | 6.30—7.30 | 8.30—8.30 |
| | 7.30—8.30 | 93.0—10.30. |
| ( Evening.) | Masses ( Benediction ) | Isin Ibukun. |
| | 4.45—5.30 | 6.45—7.30. |

### ANGLICAN.

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—St. Paul's ( Breadfruit ) | Ven Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6 30 p.m. do. | do. |
| 9. a.m.—St. John's (Arọlọya) | Rev. H. V. E Johnson |
| 6 30 p.m. do. | do. |
| 9 a.m.—St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 4 p.m. do. | do. |
| 9 a.m.—Holy Trinity ( Ebute Ero ) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 6.30 p.m. do | do. |

### WESLEYAN.

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. J. C. Cole |
| 7 p.m. | Rev. A. N. Cole |
| 10 30 a.m.—Ereko | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. do. |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. D. A. Beckley |
| 7 p.m. | " E. E. Williams |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | " E. E. Williams |
| 7 p.m. | " D. A. Beckley |

### AFRICAN ( COMMUNION.)

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | Rev. Supt G. A. Oke |
| 9 a.m.—Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 4 p.m. | do do. |
| 9 a.m.—Bethel | " G. M. Oṣọba |
| 4 p.m. | " J. K. Dawodu |
| 6.30 p.m. | Rev. E. A. Akinọla |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| 4 p.m. | " I. O. Oyekunle |
| 10 a.m.—Ararọmi Church | " A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | Bro. Joseph Bandele |

### EBENEZER.

| | |
|---|---|
| 10 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 7 p.m. | Bro. M. D. Adegboye |

### BROTHERHOOD.

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. J A. Adesanya. |
| 7 p.m. " | Pastor A. Adedeji Iṣọla. |

### AHMADIA.

5.30 p.m.—Open Air Service Prof. Maulvi Nayyar ( Vincent Street.)

## Advertisements.

IPOLOWO OJA.

—:o:—

### ILE OWO IFẸ OLODUMARE.

Ọgbẹni Onişowo M. Bankọle Fadipẹ mura tan lati ranşẹ orişirişi Ọja fun enikẹni lati ilu-oyinbo.

Ibaşe Ọja bi Ewe-taba, Ẹtu-ibọn, Awo, onjẹ-inipanu, Ẹrọ-ere ọmọde, Aşọ, ati awọn nkan bawọnni.

Enia le san Idamẹrin tabi Idameji owo silẹ gẹgẹbi iye-owo ọja rẹ ti to.

Awọn oyinbo rẹ ni ilu Germany şetan lati gba enia lawin ọja; nwọn yio si fi ọja ti o ju idameji iye owo ọja ti o ba fi ranşẹ si wọn, şowọ si ọ, a o si fun ọ laye Oşu mẹta lati san owo toku. Maşini Ọlọwọ ati Ẹlẹsẹ daradara (Ọlọkọ rubutu ti Germany) nbẹ.

Ọgbẹni onişowo yi nfi Cocoa, Ekuro, Epo ati orişirişi Awọ Ẹran şọwọ si Ilu Oyinbo fun tita.

Ẹ lọ ba orire nyin pade lọdọ Ọgbẹni onişowo yi ni Ile-owo rẹ

Ebute Oluwa.

158, Marina L'Eko.

---

### IJỌ GBOGBO ENIA DUDU,

TI IWỌ ORUN AFRICA LABẸ GẸSI.

A nşe Ipade ti Ẹka Ẹgbẹ yi l' Eko ni ijọ ẹkẹrin ọsọsẹ Alaruba, (*Wednesday*,) ni Arapa Hall, Williams Street, ni agogo marun-abọ ni irọlẹ.

Gbogbo Enia lape sibẹ.

—o—

### READY.

**"Church and Politics."**
**(A Lecture)**

OR

THE DUTY OF THE CLERGY TO THE LAITY.

BY PROF: DENIGA.

SOLD at 24 Williams Street, Lagos.
3d. a copy.

AWON ẸGBẸ OYINBO ONISOWO TI A NPE NI

E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ Enia Dudu, nwọn a nranşẹ Ọja fun enikẹni to ba fẹ'ibaşe Ọja ti Ilu Germany tabi ti awon Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe *England* ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ lati ba fi ranşẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Kosi ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki enikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi şowo lọ tabi ki o kowe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karim Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-iti Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L'Eko.

Ẹnikẹni le kowe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

### "OŞEWỌNI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aşẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

### Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street*,) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aşẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DANWO: Ogun rẹ jẹ bi idan.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.